# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE TẸNI GBOGBO LAWA

No. 715 TUESDAY JUNE 9, 1964 (2D)


## ỌLỌṢA GUN ỌGA ILE-IWE L'ỌBẸ !

TANGANYIKA:— Idaamu nla ba gbogbo awọn ara ilu nigbati ariwo ẹkun Ọga Ile-iwe kan, Omidan Irene Leack ji gbogbo wọn silẹ ni kutukutu owurọ Ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ keje oṣu yi nigbati awọn Ọlọṣa kan pade rẹ lọna ti awọn si gun un l'ọbẹ lẹhin-Ọrun.

Irohin awọn Ọlọpa Tanganyika fi ye wa pe, Ọdọmọbinrin na jẹ ọkan ninu awọn Ọmọwe ni arin ilu wọn, ti no kọju si iṣẹ rẹ on si ni Ọga ile-iwe kan ti o jẹ wipe ati Ọmọ Oyinbo ati awọn enia dudu ni o lọ sinu ile iwe na.

Oju Ọgbẹ mu pọ ti o fi jẹ wipe, Obinrin na ko le sọrọ, lẹsẹkẹsẹ ni awọn sare gbe e lọ si Ile-iwosan fun itọju Ṣugbọn ni Ọjọ na ni awọn Ọlọṣa tun gun Obinrin kan ni Ọba l'ẹgbẹ ibikan-na.

Irohin fi ye wa pe, bi Obinrin na ti ṣe jade nile ni afẹjimọ, nigbati nwọn rin jina diẹ, ni Ọkunrin na ba tọrọ Owo lọwọ rẹ, o si sọ pe Owo ko si lọwọ on.

Ki o to sọ bẹ tan ni Ọkunrin na ba gun un l'ọbẹ ti o si gbe apo apamọ rẹ lọ pẹlu Owo ti o wa ninu rẹ awọn Ọlọpa ti gbe Obinrin n alọ si Ile-iwosan nwọn si nwa Ọdaran na lọwọ bayi Bi nwọn ba si ti ri i, ẹo ma a gbọ o,

## Alhaji Balewa Sọ Pe:

# Ẹ PADA SI ẸNU IṢẸ NYIN, ỌNA ỌFUN ỌNA ỌRUN NI

EKO:— Alhaji Abubakar Tafawa Balewa, Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria ti o wa ninu isimi Ọsẹ mẹfa ti o si pa isimi rẹ ti ti o sare wa si Eko ni Ọjọ Aiku ti iṣe Ọjọ keje Oṣu yi fun "eto pataki" kan ti rọ gbogbo awọn Aṣiwaju ẹgbẹ awọn Oṣiṣẹ pe ki nwọn pada si ẹnu iṣẹ wọn "kia-kia" lẹhin na ki nwọn o ma a wa bere fun Ohun yowu ti nwọn ba nfẹ lọdọ Ijọba.

Alhaji Abubakar tun ṣe alaye siwaju pe, Ijọba ti padanu awọn nkan ti o ṣe iyebiye fun wọn ati awọn nkan ti o ṣọwọn julọ.

Alhaji Abubakar tun ṣe alaye pe ti awọn oṣiṣẹ ba pada si ẹnu iṣẹ wọn, ohunkohun ti nwọn ba nfẹ, ki nwọn mọ daju pe, nwọn ni anfani lati bare fun un lọdọ Apapọ Ijọba.

Ṣugbọn o ṣe alaye pe, Ijọba ko ni le fi ẹkunwo-oṣu gọbọi ti awọn oṣiṣẹ mbere fun nitoripe, ko si owo to bẹ ẹ ni apo Ijọba.

O tun ṣe alaye siwaju ninu ọrọ rẹ pe, Eto-idagbasoke iṣẹ ọdun mẹfa ti Ijọba fẹ ṣe wa nilẹ, owo ni Ijọba yio si fi ṣe gbogbo rẹ ki idagbasoke o to le de.

Otun sọ pe, ifikun owo ịpẹtẹ yio ba eto iṣẹ A j e orilẹ ede yi jẹ. Iba owo t i mbẹ lọwọ Apapọ Ijọba Naijiria ni Ijọba yio fi pẹlẹpẹlẹ ma bi o ti tọ afi bi o ti yẹ.



Alhaji Abubakar Balewa

Ki Apapọ Ijọba et o na abayọri eto iwadi ẹkunwo oṣu awọn oṣiṣẹ ti M rgan ṣe, nwọn ti fi ọran na han awọn Ijọba Ipinlẹ, l o r i imọran wọn ni Apapọ Ijọ ba fi ṣe gbogbo ohunti nwọn ṣe lẹhinti nwọn faramọ gbogbo rẹ.

Alhaji Abubakar tun sọ siwaju ninu ọrọ rẹ pe. bi ẹnikẹni ba kọ eti ikun si ọrọ ohun yi, ti oluwarẹ si tun huwa aibikita si ọrọ na, ki oluwarẹ mọ daju bi o ti ṣe le buru to fun on.

Ni ipari Alhaji Abubakar wa sọ pe, "Bi nkan na ba tun nlọ bi bi o ti nl yi, ti ko si si ṣi ayipada rere kan lati oni yi lọ Ijọba mi yio ṣe ohunti o ba tọ fun awọn oṣiṣẹ, ti nwọn ko ba yara tete pada si ẹnu iṣẹ w ọ n nitoripe, nkan fẹ buru rekọja idaji bayi".

"Ijọba mi ti ṣe wọn iba sunru i o le ṣe fun ẹnyin Oṣiṣẹ. Ijọba ko si tun le ṣe sunru ju eleyi lọ mọ, bi e ko ba pada si ẹnu iṣẹ yin laipẹyi. Ohun ti Ijọba ba ṣe fun nyin gẹgẹbi ṣẹria iwa aigbọran nyin ki ẹ jẹki o tẹ nyin lọran."

Irohin fi ye wa pe awọn Asiwaju ẹgbẹ oṣiṣẹ ti pinuu pe, awọn ko ni pada si ẹnu iṣẹ, gbogbo ohunti Ijọba ba fẹ ṣe fun awọn oṣiṣẹ ki nwọn sọ, ti o ba tẹ awọn lọrun, awọn o pada lọ si ibi iṣẹ, ki Ijọba o sọ ohunti nwọn ba fẹ ṣe tabi iye ti nwọn ba fẹ fi kun owo awọn.

Onirohin wa kan fi ya wa pe gbogbo awọn Oluko fakejado Orilẹ-ede yi ni nwọn o da iṣẹ silẹ ni owurọ yi.

Bi awọn olukọ ba da iṣẹ silẹ ajẹ wipe gbogbo awọn ọmọ ile iwe ni yio maa rin kiri gbaṣẹ-gbaṣẹ kiri ilu ni owurọ yi.

Ọpọlọpọ iwe irohin ni ko le jade ni ana nitoripe ko si ina lentiriki fun wọn lati fi tẹ iwe wọn,

Ṣile kan (1/-) ni awọn onimọto ngba lati Ita Tinubu de Ọbalende ni ana nitoripe awọn Onibọọsi ti da iṣẹ silẹ.



Oloy J. M. Johnson
Minista Alamojuto Eto iṣẹ

# ITAN AJIRAN ILU AWỌN OKU Apa (14)

Ka pa ti awada ti irun gbọn rẹ dabi irun ẹsin o mu herehere bi waya (wire) ti ko ba fẹ ki enia r'oju rẹ a ma a fi bo oju. Nigbati awọn Ọmọ Onilogbo ri, wọn mi pe eleru-a-sung ati pe Ogboju-le- Ogun lo fa a.

Alijannu yi bẹrẹ ọrọ rẹ bayi pe "Bi iya nla ba gbe ni ṣanlẹ keekeeke ami agori eai Iba ma ṣe bẹ ni iwọ apa ẹjọ mi. iwọ asi tun ma a ba iyawo mi tage ninu ile mi"

Bi a o ba ku ẹkanṣoṣo laa ku. Ọmọ araiye asi gbe ni sin, ma f'oko mi da ọna, ẹkanṣo la nkọ Lẹhin iku sare ni ko to wi bayi tan. o ti lewo ija kaka ki Ogboju-le-Ogun baa ja. o bẹrẹ si bẹ ẹ pe ki o dariji on gẹgẹbi ẹnyin paapa ti mọ pe, bi ẹlẹbi ba ti mọ pe on jẹbi oyẹ ki a dariji ni Ibinu ka lọju Alujannu yi, o si dariji ni. Awọn Ọmọ Onilọgbo pẹlu Alujanu yi wa di ọrẹ timọ timọ nwọn mura lati mu irin ajo wọn pọn lọjọ na, sugbọn ko gba o ni on nfẹ ki nwọn sun ti on d. Ọjọ keji ki on si ṣe wọn lalejo, ki nwọn si jọ gbadun ati wọn ki nwọn to ma a lo, nwọn gbọ, nwọn si gba.

Nigbati ilẹ ṣu, o to nkan bi agogo mẹjọ alẹ, alujannu Oloju kan yi paṣẹ pe ki a gbe onjẹ awọn alejo sori tabili Ti iyawo Agidi lati kọkọ nsọ ri, pe o mọ ọpẹ se ti iyawo Alujannu wa pa bambari, orun ọbẹ rẹ, ti enia ba ti fa asi ima lẹkan Oluwa rẹ yio yọ de Ọrun.

Irohin ko to afojuba ni onjẹ alẹ ọjọ na ko ni kan to, Koti ni dun to ti nko ba jẹki ẹmọ iru ọbẹ ti iyawo Alijọnu yi se,

Awo mẹfa ni ogbe si ori tabili ekini kun fun Iyan ti pọn lọdẹdẹ nitori isu alọ lo fi gun un ko ni ẹyọ koko kan rara.

Ekeji jẹ awo ọbẹ Owe (sikito uwe lọkọ iyan) ode ade ẹgusi, owa fi yarin seti gbogbo rẹ di ṣikiṣiki awo ọkẹta ajẹ ti ọbẹ aparo-asepọ mọ na, ẹnyin onkawe mi si ti mọ pe ẹniti oba f'aparo



Eṣu re e! Balẹ Ọrun Apadi!!

dala loni ni ki aṣi yan je awo ẹkẹrin jẹ ti ọbẹ igbin, awo karun ti ọbẹ dindin, awo kẹfa wa jẹ ti amala lafuu.

A gbe eyi kalẹ nitoripe boya ninu wọn ko ni mọ jẹ.

Gbogbo rẹ wadi kan ikami Alijọnu wa nsọ fun un pe ki awọn ma jafara nitori ọrọ wa atipe ilẹ nṣu lọ. Nwọn bẹrẹsi wẹwọ lọkọkan nigbati nwọn wẹwọ tan gẹgẹbi aṣa onilogbo. Ige bẹrẹsi gbadura o ni "Busi fun wa Oluwa ki o si jẹki onjẹ yi mu wa lara le ki ale ma sin ọ nipaṣẹ nipaṣẹ Jesu Kiristi Oluwa wa (Amin)

Lilaju ti awọn laju oi Oluwa fi han Ige gbangba pe majele mbẹ ninu onjẹ ti nwọn gbe niwaju wọn, Ige sọ fun awọn aburo rẹ nwọn ko ba nwọn fi nṣe ẹfẹ bẹni oba pe aja kan ti ọ nre gọja agba! agba!

Obu okele kan ninu onjẹ na oju si aja na koiti gbe mi tan ti o fi di ologbe. Niko si jẹ onjẹ na mọ. Ebi bẹ rẹ si pa wọn, nwọn rọ kalẹ ati ori ọkọ rẹ, ogbe nwon

Obirin yi ti takete nibi ewe ẹdundun, ati sunto nwọn ko ri Ọrun sun, nitoripe ebi npa wọn.

gbayi ti awọn ọmọ ẹhin rẹ

Ogboju-le-ogun ṣẹṣẹ wa ranti pe gari olewoyọ kan wa lapo on, nwọn da somi, nwọn mu u yo, ni nwọn ba sun lọ gbadari. O fa ṣẹrin kan yẹ ninu apo rẹ, o gba a mọlẹ. Eyi yi jẹ tọnfọn nti fọn, a sun ma parada ni ti igi aja ilẹ ni bẹrẹ si yọiyin si.

Gbogbo wọn sun lọ bamu bamu, ẹnikẹni ko taji



Lati Ọwọ J. O. Shoyinka

Gẹgẹbi ẹnyin paapa ti ao pe, awọn jagunlabi wọnyi ki i fi malu, ewurẹ, tabi agbo ṣe ajọyọ a fi enia ab-run lori.

Inu Alujannu ọloju kan dun to bẹ gẹẹ, nitoripe o ti fi enia t o yo fi d j..

Ẹṣẹpe ṣimuṣimu. Awọn iwin joko sẹgbẹ kan pẹlu olori wọn iroko, awọn Alujannu joko sẹgbẹ kan pẹlu olori wọn, arọni, awọn iwin odo joko sẹgbẹ kan pẹlu olori wọn Yemọja, awọn iya mi Oṣoronga joko sarin pẹlu olori wọn Ayun Orunbọ

Ipade bẹrẹ. gbog o nwọn pa lọlọ igba, kolu Alaga ọjọ na ni Ayọrunbọ (ẹiyẹ buburu ti njẹ larin awọn ajẹ), Igbakeji alaga ni Ogun (lakaiye Ọsinmọle Olomirirole fẹjẹ wẹ), awọn ọgbẹni iwin Iroko, sọnpọnna, ati awọn Irunmọle mẹrinlelogun lo ṣe isọngbe rẹ lọjọ na.

Eṣu lulu ọkiri oko ni nwọn fi ṣe Ọlọpa (Police) nitope ọmọ ina la iran si ina. Eṣu kapa daru - dapọ nitoripe on lo nda silẹ.

Ogun gbadura ṣoki, bẹni nwọn bi bere Ipade, Ayọ—runbọ dide gẹgẹbi alaga lati ba nwọn sọrọ. O ni i gbogbo eyin ti owa sibi Ipade yi ni mo lorukọ mi ati awọn ẹlẹgbẹ mi ti nlo ni ọrun alakeji, awọn wọn yi ko le bawa pejọ, loni, nitoripe o ni ni ọjọ ti kude degbo nṣe ọjọ ibi, ẹnikẹni niran nwọn ko gbọdọ fi ọrun Alakeji silẹ ki nwọn ma baa ri ibinu iku oni emi ti mo wa larin nyin nisisiyi nko ni pẹ lọ, toripe mo jẹ ọkan ninu awọn ti iku fi pe wa sibi ase nla yi animọ ni peregun nlaṣọ ako ni pẹdin lailai, enia ko ni pa wa, ako si ni p'enia gbogbo wọn ṣe Amin.

Ṣugbọn Eṣu ati Ogun ko ṣe Amin Ayunọrunbọ tun dupẹ lọwọ wọn fun Alaga ti nwọn fi on ṣe. Bi o ti sọro tan o joko.

Ogun bẹrẹ si sọrọ o ni, on dupẹ lọwọ Ayọrunbọ fun ọrọ ti on sọ, n tun dupẹ loruko n o ati awọn ẹlẹgbẹ on. Ti Ayunọrunbọ bade ọrun alakeji ko ki Iku dedẹegbo ati ilẹ ohun ajẹigba enia ma wukọ ẹgbọn rẹ, pe nwọn ku ajọyọ ọjọ oni, Oluwa a jẹki nwọn ṣe ọpọlọpọ rẹ, o tun dupẹ lọwọ awọn ẹlẹgbẹ rẹ, to wa sibi ipade ijoko.

**Ẹ ma ka Irohin Imọlẹ Ọloyin-Mọmọ lojojumọ.**

## Iyipada Ile Iṣẹ

Eyi nilati kede fun awọn Onibara wa pe ati ko ile itaja wa kuro ni Ibadan patapata asi ti lọ si Ilu Itirẹ ni Agbegbe Suru Lere ati Mushin.

Ẹnikẹni ti o ba fẹ bawa ra Iwe tabi Turari Ajẹbidan ẹ kọwe si ile itaja wa ni Nomba 1, Ishiba Street Odo

**Apejuwe Ile Iṣẹ Wa**

Shoyinka
c/o Postal Agent,
Itirẹ Via,
Suru Lere, Yaba

# IWE SI OLOTU

## E Tun Anikantamọ Ṣe

Olotu, Kara o le o. Inu mi yio dun pupo ti ẹ ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin alarinrin lati kesi Ijọba Ibilẹ Eko nipa adugbo wa ti o ba jẹ ti ko si ṣe rin ni asiko yi

Ẹ jọwọ Igbimọ Ijọba Ibilẹ Eko ẹ ba wa tun adugbo Anikantamọ titi wa si Olushi ati adugbo ti nwọn npe ni 'Old Arọloya ṣe awon adugbo wonyi bajẹ pupo nwon ko si ṣe rin ni asiko ti awa yi nitorina a bẹ Ijọba rere yi ki nwon o tete ba tun adugbo na ṣe, Kansilo Imoru oro na di owo yin o

A o ma reti owo yin o

Emi ni

Jimọh Lasisi

EKO

## E ku Iṣẹ o, Olotu

Mo ki Olotu Irohin-Imọlẹ pupọ, ẹ ku Iṣẹ. Oluwa ki o wa pẹlu nyin, Ojoojumọ ni a ngbadun Ọwọ nyin nipa awọn ọrọ Olotu ti ẹ ma nsọ, ti ẹ si fun awọn ara ilu ni Ọpọlọpọ imọran, paapa nipa awọn Irohin ti a ri ka ni Ojojumọ, ti a ko ba ni ṣe ete ni ẹsọ, iṣẹ nlanla ni ẹ nṣe fun wa awa na si ngbadun yin.

Oluwa yio tun bọ ma sẹ atọna nyin, ẹ ko ni lugbadi ofin Ijọba, ẹni elẹni ko ni gbaṣe yin o.

Lakotan Ọrọ mi yi. mo bẹ yin pe ki ẹ ba wa ṣe ọna bi ao ti ṣe ma ka ọrọ yẹyẹnatu ni Ojojumọ dipo Ọsẹsẹ ti a nkan.

Mo si lero pe eo ba wa se eto nipa rẹ Ao ma reti esi o.

Emi

Abiọdun Ogunlọwọ

IBADAN.

## Wundia Egiọyọpo, Ọdi Ẹwọ Yin

Olotu ẹ gba mi ni aye die ninu iwe nyin Oloyin mọmọ lati ba awọn wundia ilu Egiọyọpo sọrọ atata lori iwa oju ko gbe ibikan ti nwọn nhu ni asiko ti a wa yi iwa na ko dara to bẹni ko si ba igbomi.

O di ti iwa awọn Ọmọbinrin na lati mọ fẹ awọn Ọmọ ilu wọn mọ a fi awọn alejo ati ara ilu miran

Awọn asiwaju nyin ko hu iru iwa ti ẹ nhu yi rara, nitoripe ẹsin ti iwaju ni ti ẹhin lati wa sare ẹhin ko ṣe bẹ rara wa ti o mu nyin ni ẹ nhu si ara nyin.

Ki ẹ si tun ṣọra fun iwa ojukokoro ti o nba alafia ati anfani nyin jẹ ti o si nfa oyun elẹsinrin ti ẹ si nba Ọmọ ti ko ni baba jọ.

Mo dude lọwọ Olotu fun aye ti ẹ gba mi.

Emi ni

Amọdu

IGBAJA.

## E Kọ Ile-Iṣẹ Fun Wa

Mba dupẹ bi Olotu Irohin Imọlẹ ba le gba mi ni aye lati ba Ijọba Iwọ-Orun Naijiria ki nwọn o fun ni ni awọn nkan ti o njẹ wa niya ni ilu Ogbomọshọ.

A nfẹ ki Ijọba o kọ ile-iṣẹ si ilu Ogbomọshọ, nitori ko si iṣẹ ni ilu yi, ọpọlọpọ awọn ọmọ wa ti o njade ni ile-iwe kekere ti awọn obi wọn ko ni agbara ati ran nwọn lọ si ile Ẹkọ giga ni ki ri iṣẹ ṣe, ti Ijọba ba si kọ ile-iṣẹ ni orişiriṣi eyi yio si tundi aiko ri iṣẹ ṣe awọn ọmọ wa ku, nitorina a lero pe Ijọba rere yi yio tete ṣe eto ati kọ awọn ile-iṣẹ na.

Olotu, mo dupẹ aye ti ẹ gba mi, Iwaju ni ọpa ẹbiti yin yio ma resi o,

Emi ni,

Emmanuel Taiwo

OGBOMỌSHỌ

## EYi KO ye mi

Olotu, Inu mi yio d u n pupọ bi Olotu iwe Irohin Imọlẹ ba le gba mi laye diẹ ninu iwe rẹ ti nta b i akara gbigbon lati bere ọrọ ti ko ye mi yi lọdọ awọn ọlọgbọn ati Oloye ti nka iwe yin jojojumọ ibere na jẹ nkan ti ọ sa sumi loju inu mi yio dun pupọ bi ẹ ba le la ọrọ na ye mi.

Nigbati mo fẹ ṣe igbeyawo alọ si ile ejọ lati lọ igbeyawo (Court Marriage )a si fi ọwọ bọ iwe iwe pe, ao ni ko arawa silẹ titi ti iku yio fi ya wa.

A si nba igbeyawo na lọ ko pẹ ko j i n na edeaiyede bẹ silẹ larin wa, mo si nmu suru fun obinrin na, ṣe ẹm ọ w iwa obinrin miran

Ọrọ re o rẹpẹtẹ! olotu, oju re ko ni ribi o, b ẹ n i Olodumare ko ni jẹki poro o ọrọ rẹ ko dọya, gbogbo ẹyin onkawe mi, mo nreti imọran nyin nipa ọrọ t i o di e e w o sinu mi yi lati ọwọ ẹnyin ọjọgbọn.

Emi ni

Omo Afọgbon Sapara

AJASSẸ — IPO.


## EGBOGI JẸDIJE

BERE EGBOGI



### "CYCLOVEN"

Aworan oke yi fi han gbangba ibiti Jẹdijẹdi rẹ gbe wa lara rẹ si nyọ ọ lẹnu nigbagbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu tabi Iho idi enia ibiti a ma ngbe ṣe igbọnsẹ. Arun Jẹdijẹdi je ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun Ọkunrin ti o si lagbara pupọ lati ṣe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri lode nisiyi ti wọn maa powo wọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya la leri mẹwa ninu awọn ogun o le ṣe iwosan arun yi daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe boya bi wọn ba lọ si ile Dokita lati lọ ke eyiti o ba nyọ jade lati omusu ku ni pa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patapata.

Ṣubbọn awa ko ro be rara. Lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun obẹrẹ akana. Orişirişi Jẹdijẹdi ni o wa ekini ti o bẹrẹ nipa aiko mẹ ṣe igbọnsẹ dede tabi lojojumọ, ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna pẹlu lojoujmọ tabi gigun kekẹ ologere (Basikulu) pupọ ẹlomiran ẹwẹ nipa jijẹ Ṣuga tabi oniruru ohun adidun pupoju nigbakugba. Jẹdijẹdi orişirişi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ ade ninu omusu, tabi ti o ba nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnsẹ, tabi ti o ba nyọ ti o ba ṣe igbọnṣẹ tan ni, tabi ti nrin ọ ninu omuso ni eyikeyi ti o ba ra bere egboogi "CYCLOVEN" ti awọn Oyinbo Jamani ṣeṣẹ wa idi rẹ kio si panwo orişi mẹta ni o daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijedi patapata alafia yio de si ekeji rẹ ko si ninu gbogbo egbogi atata gboro Naijiria jakejado. Bere rẹ ni:

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji

## Ibanujẹ Tabi Ironu Rẹ de Opin Ayọ De

Bere Ojulowo Egobgi awọn Faranse gidi ti a npe ni

### 'CORSIVER'S



Ojulowo ati Ajẹbidan Atamatase Egbogi ti a ṣe ni pataki Fun „ARỌN KINIṢA" tabi LATANATAN" ti o ma mu idiwọ wa fun Obinrin lati Fẹraku tabi lati ma ṣe abiyamọ meji rẹ kosi kakiri igboro ilu Eko. Lẹhin ti o ba i lo egbogi arọn yi tan ti inu-riru, aya ririn, ẹhin didun tabi aikoto ẹjẹ lara, ẹjẹ dudu ibadi gige tabi sisan ba nyọ ọ lẹnu sibẹsibẹ bere ojulowo egbogi ti awọn Oyinbo ṣe nipataki fun AJO "OBINRIN" ti awọn amodi wọnyi ba nyọ lẹnu ti wọn npe ni egbogi na njẹ ni ṣọbu awọn.

Waterloo Stores
8, Palm Church Street, Lagos.
Phone:- 2287 Nigeria, (Ọja Ita Faji Lagos.)
ADEDUN CHEMIST
14. Wakeman Street Lagos
NIGERIAN MEDICINE STORE
Tinubu Square Lagos.]
ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:—
IṢẸ LODUNMARE DISPENSARY OKE-BỌLA

# Ko Si Ofin Isede Ipade Ni Ipine Iwọ Orun

EKO Laipẹ yi Irohin de ọwọ wa lati ọdọ awọn ọlọpa l'Eko pe ko si ofin isede ipade gbangba ni ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria. Gẹgẹbi irohin to de ọwọ wa ni ọjọ Ọjọ'Ru ti işe ọjọ kẹta oşu yi fi ye wa pe lati ọdọ ọgu Ọlọpa agba lati Eko ni irohin na ti wa.

Irohin na fi ye wa pe ofin iwọde gbangba si wa ni ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria gẹgẹbi irohin kan to wa ni nu iwe irohin Daily Times ti o sọ pe awọn ọpọlọpọ mọto ti fẹ na to le olotu ipinlẹ ila orun Naijiria, Dokita Okpara pe awọn ọlọpa kọ lati jẹ ki awọn mọto na to tẹle e lasiko irin ajo rẹ si Ibadan,

Ni edakeji ẹwẹ, irohin na si fi ye wa pe Ọpọlọpọ awọn moto lo to telẹ Dokita Okpara, şugbọn awọn Ọlọpa si da nwọn duro fun eto ofin iwọde gbagba to wa lode lati ma lọ diẹdiẹ ati awọn moto miran ti ko tẹle Olotu ipinlẹ ila orun.

Irohin na tun ti ye wa pe ko si wọde gbangba ni Ibadan ni ọjọ ti Olotu ipinlẹ ila Orun de ilu Ibadan gẹgẹbi iwe irohin kan şe sọ sugbọn ki işe Irohin-Imolẹ.

## * YẸ IRAWỌ RẸ WO *

AGUARIUS Jan 20-Feb 18 Gbogboo nkan to jẹ ti ara rẹ lo wu ọ julọ, gbọgbo ero ọkan rẹ jẹ ala ti ko ni şe. Bi o badi ọsan ija kan yio şẹlẹ larin iwọ ati oluwarẹ,

PISCES (Feb 19- Mar 20) Ki olo gbogbo ọgbọn ori rẹ si ọran ara rẹ iwọ yio ba obinrin kan se ıpade ti ẹ o ma ba ara nyin ta ọrọ awọn ẹbi rẹ kan yio ru ọ loju, şugbọn dupẹ lọwọ ori rẹ.

ARIES (Mar 21-April 19) Inu rẹ yio ma dun ọkan rẹ yio si kun fun ayọ lati le sọrọ pataki kan ti o diju Maşe jiyan lori ọrọ ti ko to nkan.

TAURUS (April 20-May 20) Ọjọ oni dara fun ọrọ ara rẹ şugbọn o yẹ ki a şora gẹgẹbi oti mba awọn 'nia nlanla pade. Irohin aladun ni iwọ yio ma gbọ loni.

GERMINI (May 21 June 21) Ọjọ oni dun o si dara fun nipa owo ati asiki iwọ yio lọ sibi ase kan nibẹ ni iwọ yio ma ba Obinrin kan ra, titi nkan yio fi kọja sinu nkan, maşe jẹki ọrẹ rẹ jowu

CANCER (June 22 July 25) Ọjọ oni le, nşe ni ki o şe snra, ki o maşe ja, bi ija ba lọ bẹ silẹ, n k a n yio bajẹ.

LEO JUly 23 Aug 22 işẹ yio d i ọ lọwọ p u p ọ loni, o nfẹ oniranlọwọ iwọ yio jere ninu işẹ rẹ n a w a Oluranlọwọ.

VIRGO Aug 23 Sept 22 Iwọ yio gbọ irohin ayọkan oni nipa ere ti o jẹ lori Ariwo diẹ yio wa bı o ti wu kio ri maşe ba awọn ẹbi rẹ sọ ọrọ aşiri kọkan.

LIBRA (Sept 24-Oct 23) Iwọ yio rin ırin ajo lọ si ọna jijin lati wo ojulumọ rẹ kan. Şugbọn iwọ pẹlu obinrin kan yio şe gbonmi si omi koto yio ma jowu si ọ, iwọ yio yayi larin ẹgbẹ ati ọgba,

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Ire ni ni gbogbo ọjọ oni yio jẹ fun ọ, Iwọ yio ri iwe gba loni o si jẹ lati ọdọ ọbinrin igbadun si mbẹ larin iwọ ati awọn ẹbi rẹ,

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 21) Gbogbo enia lo nfẹran rẹ, iwọ yio si ri iranlọwọ pupọ lati ọdọ wọn, Iwọ o ri ere nla jẹ, ohun kan ti o si ti nfẹ yio tẹ ọ lọwọ Rin faaji lọ si oJe loni,

CAPRICON (Dec 22-Jan 19) Irọrun ni ọjọ oni yio jẹ fun ọ. ọpọ nkan ti iwọ nfẹ ni iwọ yio şe ipinu rẹ, Iwọ yio jẹgbadun pẹlu olufẹ rẹ kan, agbalagba ẹbi rẹ kan nfẹ iraulọwọ rẹ


# CLASSIFIED PAGE

"KIU FUNG MANUFACTORY BOX 3812, HONGKONG, IMITATION JEWELLERY WIRE HOOKS"

# MODUPE PRINTNG PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING

*Many Firms Patronise* MODUPE PRESS *Because Of Their;—*

MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHODS OF PRINTING

*For Your Next Printing Jobs:—*

Just Call 21985 - Leave the rest to Modupe

We Guarantee Neat Work And Quick Service

**Modupẹ Printing Press**

**16, Bamgbose Street,**

Phone 21985, Lagos.

# SEDO— PAYAL

Ojulowo Egbogi kokoro ti o lagbara gidigidi fun 'Ipara" ti awọn ilera tabi amodi wọnyi ba nyọ ọ lẹnu lode ara, ọwọ tabı ẹsẹ hihun tabi yiyun nigbakugba, A'efọ, Egbo ẹsẹ orişirişi tabi ti ọjọ rẹ ti pẹ bi adain egbo ekusẹ tabi ekusẹ tabi lapalapa. Ela tabi ara su,Akọ, inarun ati orişirişi orun "Are" miran gbogbo





Gbiyanju lati dan egbogi tiiun awọn ara Ilu Tatanb ruaşe ti nwọn npe ni "PAYAL" wb larin ọjọ mẹta run a yio ma rohin rẹ fun awọn ẹlomiran pẹlu Egbogi b a yi ki şe awọn rọ irobi ti wọn nta kakiri ilu ni owo pọku. Ojulowy egbogi orun arun ara haunhaun tı ko si şişẹ ye meji ninu eleyi si yatọ patapata si awọn ẹgẹrẹmiti adimọwọ ti wọn nta kakiri ıgboro ati ni agbereko gqogbo pẹlu Orisi meji re lo wa Kekere ati Nla.

Bere egbegi Ajẹbidan SEDO PAYAL yi ni şọbu awọn 'PILENAB MIXTURE,

Egboigi olomi dara julọ fun awọn ọmọde ti jẹdijẹdi bi ako gbonse dede ba nyọ lenu bere rọ ni

WATERLOO MEDICINE STREES
FAGBEWESA STREET, OSHOGBO.

# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 715 TUESDAY, JUNE 9, 1964 (2D)


## Ijamba Ṣe Ole, Onile Ka a Mọ!

YABA Ogun gba gbogbo enia ti fun ọdọmọ dekunrin kan, Oluwọle Jeremiah ẹni ọdun mejilelogun ti awọn Ọlọpa mu mu wa siwaju Adajọ Agba ile ẹjọ kekere Yaba, Ọgbẹni E. A. S. Oguhmuyiwa, ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹfa oṣu yi fun ẹsun ole jija ati ile fifọ.

Ọlọpa ti o ba ọdaran na ṣẹjọ ṣe alaye fun ile ẹjọ pe, ni ọjọ ọjọ kọ ti i ṣe ọjọ kerin oṣu yi ni Ọdaran na lọ sinu ile kan ni nọmba 25 Aiyetoro Street, Ebute Mẹtta nigbati gbogbo awọn ara ile na ti lọ si ibi iṣẹ, ni Ọdaran na ba fọ ilẹkun iyara Ọgbẹni Sikiru Tijani, o si ko gbogbo awọn ẹru inu ile na ti iye owo wọn jẹ ponun meje ṣile meje ati kọbọ mẹfa. (£7 : 7 : 6d)

Nigbati ọdaran ṣi apoti, t i o tun r i owo kan nibẹ ponun mẹwa ṣile mẹdogun atii sisi (£10 : 15: 6d) o tun k o gbogbo rẹ ṣugbọn bi o ti fẹ ma a lọ, ni ẹnikan de ninu awọn ara ile na, nigba'i o si bere ibiti o ti ko awọn ẹru na ko le da wọn lohun, ni nwọn ba mu ọdaran na lọ si Teṣan Ọlọpa pẹlu awọn ẹru ọwọ rẹ.

Nigbati ọdaran na rojọ, ti o si gba wipe, on jẹbi ni adajọ Agba na ba ṣe idajọ pe, ki o lọ fi ẹwọn oṣu mejila jura, ki Ọgbẹni Tijani o si ma a k o awọn ẹru rẹ lọ sile.

# AKINTỌLA FẸ ṢE'BẸWO IPINLE ILA ORUN

IKẸJA:— Ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹfa oṣu yi ni Oloye Samuel Ladoke Akintọla,, Alakoso Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ati Olori ẹgbẹ Dẹmọ sọ ni Ibudo'kọ ofurufu pe on fẹ ṣe ibẹwo Ipinlẹ Ila Orun Naijiria lẹnulọloyi.

Oloye Akintọla sọ ọrọ yi ni gẹrẹ ti o ba ọkọ ofurufu, gunlẹ si Ikẹja.

O tun ṣe alaye pe, o jẹ ohun iyalẹnu pe, Dokita Michael Okpara ko sọ fun on pe, on mbọ wa ṣe ibẹwo Ipinlẹ Iwọ Orun, o ni nitori idi eyi ni ko jẹki o ba on nile.

O tun ṣe alaye siwaju pe, ti o ba jẹ wipe on ti gbọ tẹlẹ pe Okpara mbọ tabi ti o ba sọ fun on ni, on ki ba duro de e nile; ṣugbọn ninu iwe irohin ni on ti gbọ pe Okpara mbọ wa ṣe ibẹwo Ipinlẹ Iwọ Orun.

Oloye na tun sọ siwaju pe, ti o ba jẹ wipe Dokita Okpara sọ fun on ni, gẹgẹbi o ti ṣe jẹ "ọrẹ" on pe on mbọ, o ni on iba ti mọ ọjọ ti mbọ, o ni on iba ti mọ ọjọ ti mbọ ti awọn iba si ṣe eto lati ri ara awọn ati ibiti awọn o ti rira ninu irinajo rẹ.

Ni ipari ọrọ rẹ fun awọn oniwe irohin Oloye Akintọla ni o jẹ ohun ẹdun ọkan pe awọn mejeji ko le fi oju kan ara awọn nigbati o de ile on ni Ibadan.

Ni ipari ọrọ rẹ, Oloye Akintọla sọ pe on na fẹ lọ ṣe ibẹwo awọn enia Ipinlẹ Ila Orun Naijiria lẹnulọlọyi ki on si fi oju kan awọn enia na.

Ṣugbọn Dokita Okpara ti da Oloye Akintọla lohun ọrọ rẹ pe, kosi ohunti o le da Oloye na duro lati ṣe ibẹwo Ipinlẹ Ila Orun Naijiria nigbakigba ti o ba fẹ.

Dokita Okpara tun ṣe afikun pe ti Oloye Akintọla ba mbọ Ijọba on ko ni ṣe ofin pe ko gbọdọ si ipade ode gbangba tabi iwọde gẹgẹbi Ijọba Oloye na ti ṣe nigbati on (Okpara) fẹ wa si Ipinlẹ Iwọ-Orun.

Ni ipari ọrọ rẹ, Dokita Okpara sọ pe aye wa ni gbogbo igba ti Oloye Akintọla ba fẹ wa ṣe ibẹwo awọn enia ni Ipinlẹ na, ṣugbọn o ṣe afikun pe, o yẹ, o si tọ ki Oloye Akintọla kọkọ ṣe ibẹwo awọn enia Ipinlẹ rẹ na ki o si ri bi awọn enia na fẹ ṣe Ijọba rẹ tabi tipatipa ni nwọn fi nṣe tirẹ.

Dokita Okpara ni on da imọran pe ki o kọkọ ṣe ibẹwo awọn enia tirẹ na ki o to wa si ọdọ on nitoripe "Ile ni ati iko ẹṣọ re ode.


## "Figurana"

Jẹ ojulowo egbogi ti awọn Jamani ṣẹṣẹ ṣe iwadim fun awọn ti o ba sanra tabi ti o ba 'TOBI' julati ri mu ki nwọn le fi jọnku lai si wipe nwọn ma ka ewọ onjẹ ti nwọn yio ma a jẹ rara, bẹ sini ko lewu ni li o fun enia rara, yala Ọkunrin tabi Obinrin.

Ki enia sanra, gborin, tabi ki o tobi pupoju, ki nṣe ohun ti o dara rara, ọpọlọpọ amodi ni onko ba, enia bi Lakuregbe, Aiko le gbera nilẹ bi o ba joko Aiya lile kiki tabi jija nigbana, Aiko le mi kan lẹ daradara Ara wiwo, tabi wiwuwo, Emi mimi họ-họ orişirişi amọdi miran pẹlu.

Ṣa dan Igo rẹ kan wo, Iwọ y o ri ayipada ati alafia yio desi Bere ni Ṣọbu awọn Elegbogi Jamani ni igbor ilu Eko.

Adedun Chemist
14, Wakeman Street, Yaba

Waterool Medicine Store
8, Palm Church Street, Lagos
Phone:- 2287 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TỌNIKI

ALE-BI- Egbogi Tọniki Jamọnu titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan iṣẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo.

Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala tab şişẹşe ti o ko le jẹun daradara, tabi ki o male sun daa da ọkun lọsan tabi loru tabi awọn işan ara rẹ gbogbo ki ṣe fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunlẹ daradara wọn iṣẹ tabi wahala şişe tabi fun awọn ailera gbogbo enyin ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja Ọgbọn ọdun o si de adọrin tabi jubẹ lọ. Mo dupẹ "DYNAMIREN ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara di ọtun patapata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bẹ s'i dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kankan nigbakugba y'Arẹ" nigbakugba yio salọ pẹlu. Igba-dun ati alafia diro de ọ. Iyẹn daju. BereEgbogi na ni Ṣọbu:a

ADEDUN CHEMIST
14' Wakeman Street, Yaba
WATERLOO MEDICINE STORES ;
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone 2287 Nigeria (Ọja Ita Faji Lagos)
NIGERIAN MEDICINE STORES
Tinubu Square Lagos



Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos Phone:- 21985
Editor:- TUNJI ADEỌSUN 45, Campbell Street, Lagos (9/6/64)